# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No 1,568 WEDNESDAY NOVEMBER 24, 1965 (2D)


## Nwon Yinbon Pa Oga Awon Olopa Kan

APOMU:— Gbogbo enia ilu Apomu ni ẹkun lo Ọshun bẹrẹsi sa asala fun ẹmi wọn nigbati iṣẹlẹ nla kan ṣelẹ ni ilu na lori ija nla kan to bẹ silẹ larin awọn ọlọpa ti Ijọba ibilẹ ti ẹkun ọshun ati awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu kan eyiti awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu na yinbọn pa ọga agba awọn ọlọpa ti ijọba ibilẹ kan ti igbakeji ọga agba awọn ọlọpa Ijọba ibilẹ na si tun fi ara gbọgbẹ ninu ija nla to ṣlẹ ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kejilelogun oṣu yi.

Ohunti ọ fa iṣẹlẹ nla wa ni rogbodi yan kan to bẹ sitẹ ni ilu Apomu eyiti awon ọlọpa ti ijoba ibilẹ ekun ọshun fi lọ si ilu na lati lo ṣe ona gẹgẹbi ro gbodiyan na yio lọ silẹ tabi yiọ fi dopin

Nigbati awọn ọlọpa to lọ ilu na de si ilu na nwon tun gbọ wipe okan ninu ọga awọn olopa na pe awon enia kan ti ji ọlọpa na gbe ati pe nwọn ko mọ ibiti o wa.

Irohin fi ye wa pe gẹgẹbi awon enia na ti ri awon ọlọpa na ninwon bẹrẹsi ni bura silẹ de won eyiti awon ọlọpa si tun gbiyanju lati tu awọn enia na ka ṣugbọn awọn enia na ko sa fun awọn ọlọpa na eyiti o fa ija larin awọn ọlọpa na pelu awọn enia na.

Bi awọn enia na ti nba awọn ọlọpa na ja ti awọn ọlọpa tun koju ija si wọn eyiti awọn enia fi yinbọn pa ọga awọn ọlọpa na ti ọkan ninu awọn ọga awọn ọlọpa na tun fi ara gbọgbẹ.

## MORONU SỌ PE:

# GOMINA GBỌDỌ YỌ AKINTOLA KURO

EKO:— Ninu irohin kan to de ile iṣẹ wa lati ọwọ Akapo ẹgbẹ ọdọ Alakukọ ti a npe ni Zikist Movement Oloye F. M. Moronu ti kesi Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Oloye Ọdẹlẹyẹ Fadahunsi pe o ti gbọ gbogbo awọn aiṣe deede to wa ninu abayọri idibo si Ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria eyiti nwọn di ni ọjọ kọkanla Oṣu to kọja lọ yi eyiti o jẹ wipe o tun mu ki gbogbo nkan nbajẹ si ati pe ki o tete mọ ohunti yio ṣe lori ọrọ ibo na.

Oloye F. M. Moronu tun ṣe alaye pe ohunti o ṣe pataki julọ ti o tọ ki Gomina Ipinlẹ na ṣe ba yi ni ki o tete kesi Oloye S. L Akintọla lati fi ipo rẹ silẹ gegẹbi Alakoso Ijọba Ipinle Iwọ Orun Naijiria nitori pe ọna ti nwọn gba yan ijọba Ipinlẹ na ni ko ba oju mu ati pe ko ba eto ofin mu rara.

Ninu irohin ti o jade lati ọwọ Oloye Moronu eyiti o kun oju ewe iwe meji ni o ti ṣe alaye pe Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria si jẹ ilẹ ogun bayi ati pe Alakoso Ijọba Ipinlẹ na ati awọn minista rẹ lo jẹ pe nwọn ko le rin gẹgẹbi o ti nn wọn eyiti o jẹ pe l'ọsan ati l'oru ni awọn Ọlọpa si nṣọ wọn lati ọjọ ti nwọn ti ṣe idibo ni Ipinlẹ Iwọ Ornn Naijiria.

Oloye Moronu tun ṣe alaye pe ati igbati nwọn ti ṣe idibo to kọja yi ni o jẹ wipe nwọn ti ba Orilẹ ede Naijiria jẹ ni ilẹ Okere.

Oloye F. M. Moronu tun ṣe alaye pe awọn ati Ṣọja ni Orilẹ ede Naijiria lo jẹ wipe nwọn gbe iṣẹ nla fun wọn ṣe ati pe ninu ewu nla ni awọn Ọlọpa na si wa bayi lori abo ti nwọn si tun ṣe ọna bi eto alafia yio fi wa ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Oloye Moronu tun ṣe alaye pe ni ọjọ keji sẹhin ti nwọn ṣe eto idibo si Ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ni Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria Alhaji Abubakar nsọ pe ko si rogbodiyan kankan ni Ipinlẹ Iwọ Orun lori abayọri idibo si Ile Igbimọ na.

O tun ṣe alaye pe lẹhinti o di oṣu keji ti awọn enia Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria dibo eyiti o jẹ wipe ibo ti o mu oju ti enia ni nwọn ṣe ni Ipinlẹ na ti ko tun si Ijọba kankan ni Ipinlẹ na bikoṣe wipe awọn Ọba ti nwọn jẹ ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ lo nsọ pe awọn ni Igbẹkele ninu Ijọba na.

Oloye Moronu tun ṣe alaye pe lori ọrọ to jẹ pe Gomina Ipinlẹ Iwọ Orun ti gbọ lati ẹnu Alaga Igbimọ eto ibo Ọgbẹni Eyo Esuṣa pe aiṣe deede tabi jibiti wa ninu eto idibo to kọja yi o ni eleyi to lati fi han fun Gomina Ipinlẹ na ti o sọ tẹlẹ pe on ko gbọ pe aiṣe deede wa ninu abayọri idibo ti o kọja lọ yi ati pe lati fi mọ daju pe ọna jibiti ni eto abayọri ibo

WO OJU EWE KẸFA



Aworan awọn omobinrin ti e nwo loke yi ni ti diẹ ninu awon omobinrin ti nwon ko ẹko nwon pari ninu Ile ẹko nla Unifasiti Ibadan ni ipari oṣẹ ti o koja lọ yi, ti awon omo na si gb'oye imo ẹko ijinlẹ ninu ile ẹko na.

Awa Oniwe Irohin Imolẹ ki awon akẹko na ku Orire a si tun gbadura pe ki Ọlorun jẹki nwon le ri iṣẹ rere ṣe. Ẹ ku Orire o, Ẹ ti lo wa'ju !

# EJE JESU WE'WA NU KURO NINU ESE

Oro Iyanju mi si gbogbo e ia ninu ose yi, uro lori, "Ipe" ti Jesu Krist Oluwa wi, pe, Emi ati Ire ninu agbo Re, gegebi Paul Aposi eli ti wi ninu oro re si awon ara Heberu 3: 13, "Io ma gba ara ayin niyanju lojojumo nigbati a npe loni"

Loni ni, Paul Apositeli, so fun awon ara Heberu ki se ola tabi otunla, odun kan, tabi opo odun ki se igbati enia je olowo tabi olore, Borokini, onile tabi onile, Oba tabi Ijoye, mini sita tabi Olori Ijoba sugbon

on loni, Nitorina mo be o Iwo omo enia ti a fun ni anfani lati ka eko ti ose yi, ti se Ipe, fere Krist, mase ko ipe na, leti se ti Jesu Kristi lati isisiyi lo mase fi akoko da ola, tabi igbami ran. E gbo gegebi Dafidi ti so ninu orin re, o ni "Loni bi enyin o ba gbo ohun Re, E mase se okan nyin le" Psalm 96: 7 8 mo be o, Iwo oluka oro Olo run yi, ti a da Emi pe si titi di owuro oj oni mo daju pe agbara re ko lo mo o di ojo oni, nitorina mase fi akoko da ola, lati je Ipe Kristi sinu agbo Re, nitori kini yio wu ti o le wa

Gbo ohun ti Iwe Oniwa-su so ninu ori 27 ese 1; o ni "mase ileri ara re niti ojo ola, nitori Iwo ko mo ohun ti ojo kan yio hu jade; bi eyi ba ri be wa je Ipe Kristi loni sinu agbo Re.

Wo awon ohun ti o ti se le, lati ehin wa, wo bi le tutu ti se nwo, ti Ile gbigbe wa ni iduro, wo bi ojo ti o ro sehin ti Ile ti fe mu tani ninu awon wonyi ti o ti koja lo si aiyeraiye tabi ti o ti ku ti o le so wipe on mo,

igba ati akoko, ti Ipe kehin dun ti omokunrin sun ti o ko ji tabi omobinrin sun ti ko ji ta ni agbe wo ni ole so aro kehin oko, Sunday wo lo mo ti o mase k hin ojo aiye re tabi Jimo ... lo ... ba wi ki? so fun mi tabi ki o bere lowo ara re, Bi o ko ba ti dahun esi yi jowo tete je Ipe ... ni ... apojo ... ninu agbo Krist mase to pe kosi owo to ... le mu ... wa, Ranti po Obinrin ... Jesu Kristi ... Mak 12 4 3, ... ti o wa ... Olorun mo je Ipe Krist nik, bin o de orun

rere mase se bi Olorọ ni tio so wipe o di igbati on ba ni ohun gbogbo tan ki on tole je Ipe Jesu Krist ohun na f ... pe Iwo asiwere ti a-ra yi ... emi re lo ... le ori Luku 12: ese 15-20

Jowo Iwo ti a da emi re si lati ka Iwa ti ti ose yi ti o duro lo Ipe ti Jesu Kri-st npe o loni mase wa ... ki ni ori Iwe ... we so bayi pe

Emi ... wi tio ... orun ki yio parun ni ojiji

owe 29 ese 1

Adura mi si enyin oluka oro Iyanju mi nipe Oluwa mase je ki e wa orun ki Oluwa mase je ki e parE Amin

Kini awon ohun ti o le fa o sehin lati je Ipe Jesu Krist ninu agbo re? A nfi egan se Idanwo fan e bi? A LATI OWO

**M. A. O. Adekoya**

re larin Egbe tabi Ijo enia Olorun Awon enia ti ko to nti o se yeye bi A ko nan oro ati Imoran re larin Ijo gbiyanju lati wo Jesu Krist eniti o pe o si Ilana re lati je okan ninu awon ... gutan je nitori on w pe Emi ko wa Iyin enia bikose Iyin ti

Olorun nj bi Jesu Krist nfi ebu ati egan se Idanwo fun e A nso ibi s ise rere eniti o pe o, ba wi eyi kini ohun ti o pe so nigbakehin re lojo ti akuko yio koo le hin omokunrin tabi omo bi rin

Jowo ronu ni akoko yi Iwo eniti a da Emi re s ... di ojo oni lati ka oro Iyan ju ti ose yi nit ri Ol run mimo ... bay pe:-

Wa nigbati Krist npe o
Wa mase rin ... ese ... o
Wa tu gbogbo ohun t de o
Wa bere ... je tOro
Egbe: O npe o n sis yi
Gbo b'Olugbala t npe ...
2 Wa nigi ati Kristi mbe ...
Wa ... bo ohun if Re
Wo o ko ohun ife Re ...
Wo o si ma sabo ...
Egbe: O npe o nisisiyi etc

WO OJU EWE KARUN

# Iranti Ajoyo Ajo-dun Kejidinladota

Irohin ko to afojuba ni are.aladun ti awon omo ogun Soja ati awon Olopa se ni ojo Aiku ti ise ojo keji osu yi nigbati awon enia orile Rosia nse iranti ajoyo ajodun odun Kejidinladota ti awon enia orile ede na gba Ominira.



A ... ran ti e nwo loke yi ni ti awon Soja ti awon nsere kakiri gbogbo ode ni ojo na ni dagbo kan ti nw n npe ni RED SQUARE ni olu ilu Rosia ti nwon npe ni Mo-s ... ojo na Irohin fi ye wa wipe yika gbogb enia agbaiye ni aw n enia ... sile ede ile Rosia se ... ye ... d n na ni ojo na pa julo ni gbo bo ori'e ode ti Rosia gbe tini awon As ... Ij ...

Awo ... ti e n o loke iwe yi ni ti awon Soja ti nwon yika gbogbo ilu ni ojo na

# AWỌN OBINRIN ỌLỌJA ABẸOKUTA J'ARE ẸJỌ

ABEOKUTA:- Ni opin ọsẹ to koja lọ yi ni Adajọ agiba ile ẹjọ kekere ti ilu Abẹokuta ti ni ki awọn obinrin ọlọja ẹgbẹ UPGA ọgbọn ti ilu Ifọ ma a lọ ni ayọ ati alafia ati pe nwọn ko jẹbi ẹsun ti ọlọpa mu wọn wa si ile ẹjọ fun

Ninu esun ti Ijọba mu awọn obinriu ọlọja ilu Ifọ ni ẹkun Abẹkuta na fun nipe awọn obinrin na gbero lati da rogbodiyan silẹ ati pe nwọn fe ba alafia ilu jẹ

Ninu ọrọ ọlọpa to ba awọn obirin ọlọja ṣẹjọ ni oti ṣe alaye fub ile ẹjọ pe ni ojo ẹkedogun oṣu kẹwa odun yi ni awon obinrin na bẹrẹsi ni wọde kakiri ni ilu Ifo eyiti o le da rogbodiyan silẹ ati pe nwon si fẹ b. eto alafia u

Ninu oro Agbẹjoro fun awon obintin oloja ti nwon tun jẹ omo ẹgbẹ UPGA na ni oloye Toye Coker ti ṣe alaye fun ile ẹjo na pe awon enia na ko ẹjo kankan l ti fi ro niwaju ile ẹjo ati pe nwon k si jẹbi gbogbo ẹsun ti Aba nirojo Ijoba ka si awon obinrin na l'ẹṣẹ.

Oloye Toye Coker tun ṣe alaye fun ile ẹjo na pe ki Adajo ile ẹjo na da nwon en a na si ki nwon ma lo ni ayo ati alafia nitoripe nwon koni ẹjo kankan la tiro niwaju Ada o N nu idajo ad'jọ agba ile ẹjo kekere na ogbẹni C. Abin bola nio ti ṣe alaye pe on gba gbogbo oro ti A bẹ joro fun awon obinrin na ro niwaju ile ẹjo pe awon obinrin na koni ẹjo kaukan l ti ro ati pe olo o ba awon obinrin na ṣẹjo ti ku na lati ṣe al yd lori ohunti awon obinrin na fi jẹki ẹsun ti efi an won ati ni ona ti awon obinrin na pe lati fi ni ẹjọ lati r niwa ju ile ẹjọ na

Adajo agqa ile ẹjo na ọgbẹni C, Abinbol tun ṣe elaye ninu idajo re pe on da awon enia na sile lati ma lo sile won n ayo ati alafia itori pe awọn ko ni ẹjo kankan lati ro Niwaju ile ẹjo na

## Onimọto Kan Fi Ewọn Ọdun MeJi Jura

EKO:— Ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu yi ni Adajọ ile ẹjọ kekere ti Eko paṣẹ pe ki okunrin Dirẹba kan Lamidi Ishọla ẹni ọdun mejidinlogoji ya rara nlọ fi ẹwon ọdun meji jura pẹlu iṣẹ alaṣẹ kan

Lẹhinti Adajọ ile ẹjọ na paṣẹ pe ki ọdaran na lọ si ẹwon ọdun meji ni o tun paṣẹ pe ki nwọn na ni ato ri mẹfa ni idi ati pe lẹhin ti o bapari ẹwọn rẹ tan ki o tun wa labẹ amojuto awọn Ọlọpa fun odidi oṣu mejila lori ẹṣẹ ti ọdaran na ṣẹ

Okunrin ọdaran na tun bere lọwọ Ọlọpa ti Adajọ ile ẹjọ na sọ fun pe ki o mu lọ si ọgba ẹwọn pe ki ni Adajọ fi ṣe idajọ on ? Ọlọpa na si ṣe alaye fun okunrin onimọto na pe Adajọ to paṣẹ pe ki o lọ si ẹwon Lẹsẹkẹsẹ ni okunrin ọdaran yi si bu sẹkun

Ninu ẹsun ti nwọn ka si ọdaran na lẹsẹ ni Ọlọpa to ba ọdaran na ṣẹjọ ti ṣe ala ye fun ile ẹjọ pe okunrin ọdaran na Ishọla lọ ji ẹyin adiẹ eyiti gbogbo rẹ si jẹ dọsini meje ti iye owo rẹ si jẹ pọnun meji £2) ati pe ọdaran na tun ji ṣile mẹta pẹlu eyiti iṣe ti Ọgbẹni Amusa Ologunde ti Opo po Awolọwọ Road, Ikoyi ni ọgb nijọ oṣu kẹwa ọdun to kọja lọ yi

Ninu oro Ishọla ti o sọ lati fi gba ara rẹ silẹ ni o ti ṣe alayefun ile ẹjọ pe on ko jẹbi ẹsu ti ile ẹjọ na fi kan on ati pẹ on ko mọ akoko ti on ṣẹ ẹṣẹ na

Okudrin odaran na tun ṣe alaye fon ile ẹjọ pe ni ọgba ẹw n ti ilu Ijẹbu Ode ni on wa lasiko ti wọn sọ pe on ṣẹ ẹṣẹ na ati pe os ko mọ nkankan nipa ẹnun ti ile ẹjọ fi kan on

Ninu ak silẹ Ishọla lori ibiti o ti lọ si ẹwọn ati asiko ti o ti lọ si ẹwọn kẹhin ni nwọn ka si eti Adajọ ile ẹjọ pe ninu ọdun 1961 ati 1962 ni ọdaran na ti lo si ẹwọn oṣu mọjidinlogun kẹhin

Ọlopa to ba odaran na ṣẹjọ ti ye ile ẹjo pe fun opolopo asiko lo jẹ wipe okunriu odar n na Ishola ma yi oruko rẹ ti ibiti o ngbe pada lati le fi m an awon enia jẹ ati paapa julọ awon Ọlopa ti nwon ba mu fun ẹṣẹ kan

Ninu idajọ Adajọ ile ẹjọ na ri o ti ṣe alaye pe ko si ohu ti o le lati ṣe idajo lori Iṣhola ati pe e eyi si ti han gbangba pe otitọ ni odaran na ji awon ohunti Ọlọpa to ba nṣo ẹjọ kana si l'ẹṣẹ.

Adajọ ile ẹjọ na si ṣe idajọ ọbaran na gẹ ẹbi a ti ṣe alaye si oke iwe yi


# Kere o Kere Akiyesi PatakI




Awa na le jẹri wipe Ojulowo hannuhan Egbogi LEOPILLS awa na nlo ni Gold Coast (Ankara Ghana pẹlu meji rẹ ko si ninu gbogbo orisirisi Egbogi ti o wa ni Ile Naijiria

A wa na njẹwọ ni Igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia tọmọde t'agba ni asiko yi ti nwọn fi ṣe ọrọ ati orin larin ara wọn nipa Egbogi Jamaci olokiki yi ti nwọn npe ni LEOPILLS

Imọran awọn Dokita Oyinbo ti nwọn nṣe iwadi Egbogi LEOPILLS, yi kan ṣọ wipe bi o ti lagbara to ati bo jẹ Oj ulowo giriki ati atamatase fun "JẸDIJẸDI" bi o tiwu ki ọjo rẹ pẹ to bẹ na ni nwọn si tun fi ọwọ sọya tabi pe ileri fun gbogbo awọn ti amudi tabi iju, Igbẹ sise, asiko ri igbonsẹ dede, inurirun n gbakugba ara wiwo, Ẹsanro ẹhin didun s'san ati aika riran kedere ko d ro buruku lara, aisan Onigb meji ati orisirisi arun miran gbogbo pẹlu

"Wipe nwọn yio ri alafia ni kiakia ti nwọn nba lo egbogi LEOPILLS nitoripe o tun ma tun ẹjẹ ṣe lar enia nipa siso di ọtun.

RANTI PE ALAFIA LOGUN ỌRỌ IJAFARA SI LEWU PẸLU.

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:— Igo nla ṣile mẹfa abọ (6/-6 pere Igo kekere ṣile mẹta abọ (3/6) pere. Ber Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi A nta ti e ba fẹ n Ṣọbu awọn:—

WATERLOO MEDICINE STORE
8, Palm Church Street Phone 22787
LAGOS

# Shoyinka Ki Nyin O

Ki nɡto bẹrẹ ọrọ mi
O yẹki ki nki nyin pe
Ẹ ku lallai
Ẹ ku atijọ
Ẹ ku afẹrẹ yi
Ẹsi ku rogbodiyan ilu wayi
Ọba alanu, a ṣe kamaku
Yio sọ gbogbo
Rẹ 'Dẹrọ

x x x x x x

Adaṣe nii hun ni
Iba kii hun enia
Iba ni Ij mere ko di
Nigba iwaṣẹ
L'ọwọ araiye
Fi tọwọ rẹ b'epo
Mo juba ki
Iba t,emi Ko ṣe
Tori ṣiṣẹṣiṣẹ ni
T'alakọṣẹ
Iba ki iba temi
K'o ṣẹ o

x x x x x x

Iba Awo Akọda
Erinmi l'alẹ Ifẹ
Pẹpẹ nile Asin
Iba awọn Iya mi
Oṣoroga hiohio
Omi gbigbona
Ti ko ṣe bu mu
Edumare ma
Fi wa le wọn lọwọ
Iba ilẹ Ohu u
Atẹrẹrẹ k'aiye
Alapo Ika
Ajẹ igba enia ma wikọ
Odua ma jẹki
Ilẹ gbe wa mi
Laipe ọjọ Aṣẹ

x x x x x x

Iba baba to bi mi lọmọ
'yẹru Ọkin Ọmọ Ọlọffa.
Iba Iya to wo mi d'agba
Ara Inisa Ọmọba dudu ẹkọrọ
Mo juba gbogbo awọn
Oniwe patapata
Iba ki iba temi ṣẹ o

x x x x x x

Ẹ ku ipalẹmọ ọdun

Oju gbogbo wa ni
Yio ṣe o
Lagba a Baba
L'oke



Ọgbẹni J. O. Shoyinka

Ọdun yo ki si ni
D wa m'ẹrin
Lagbara Odua Aṣẹ
Odi gba kanna o.

x x x x x x

Akiyesi:—Gẹgẹ i iṣẹ mi lọdun moki ofẹ lukuluku ẹnyin onkawe lioh n lmọlẹ fi Orukọ ati adirẹsi nyi ranṣẹ si mi fun ẹbun ọfẹ ti iṣe „AGBARA IWAṢẸ WIBẸJẸBẸ" ki ẹ maṣi ṣe gbagbe lati fi stamp 2d ranṣẹ pẹlu rẹ lati le fi gbe pada si ọdọ yin·

Fi ranṣẹ si :-

SHOYINKA
P. O. Box 159
MUSHIN

## IWE KOṢEMANI NI EYI

IWE ITOṢẸ OHUN GBOGBO
NINU ODU MẸRINDINLOGUN

Iwe yi kun fun Asọtẹlẹ ati wipe, yio din ọ lowo "YẸMIWO" ku, nitoripe iwọ na yio le ma da ṣe AYẸWO fun ara rẹ

"KOṢEMANI" ni iwe na, 2/6d pere ni a nta Postage 9d tete lo ra tirẹ ko to tan

FI OWO RANṢẸ SI :-
ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8, Idumagbo Avenue,
LAGOS NIGERIA
(Leti Ọja Jankara L'eko.

## Ha! Kini Ieyi O




OGUN A PA YANMU—YANMU
OLORI ERIN MẸTA NI

Three elephant Brand mosquito coils dara pupọ, A ni o dara ju gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ.

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia oorun rẹ si dara pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ. Bakanna ni o si tun yara pa ayan ati idun.

Tete lọ ra packet ogun yanmuyanmu Three elephant Brand coils tire loni, ki o si dan wo, iwọ yio ri bi yio ti ṣe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọn ọmọ rẹ yio si sun daradara

Ki ori daju pe ogun yanmuyanmu olori erin mẹta yi ni nwọn mu fun ọ

Three elephant mosquito Brand coils yi wa ni ṣọbu ati ile itaja kakiri orilẹ ede yi.

*DISTRIBUTORS*

**Amos GBENLE & BROTHERS**
34, Docemo Street, Lagos
6 & 11 Balogun Street. West
LAGOS

## APAS RHUMATC & DRAGES

Jẹ ojulowo hanunhanun egbogi Jamani to lagbara gidi gidi fun Iwosa "LAKUREGBE" to mba enia ja

Orişirişi lakuregbe ni o wa lakuregbe Arungan ti o ma nsan enia ninu egungun ara lakuregbe ti o ma nwu enia ni ẹsẹ roboto ti o njẹki ẹsẹ wuwo lati ma rin Lakuregbe ti o ngbẹ rikerike danwo kori bi o ti roun lati lo tabi ki o ma ṣe ayipada ẹsẹ, ara rira bi eyiti enia fi ara obẹ pa ibadi abi egega ra wiwo, ako iba a p pon tabi rirun.



Bi enia ko ba gbajumọ lati toju rẹ lasiko o le so owo pa enia

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, Tinubu Square Lagos

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palm Church Street Lagos
Phone:- 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

